# Gbáradì, Ṣetán, Bèrè!



## Gbígbáradì fún Ilé olowopooku ní NYC

NYC Housing Preservation & Development | Consumer Affairs

# Àwọn Àkóónú


1 — Kọ́ nípa àwọ̀n ẹ̀yàn ilé olowopooku rẹ
ojú-ewe 3

2 — Gbáradì láti bèrè
ojú-ewe 5

3 — Bèrè
ojú-ewe 8

4 — Gbáradì tó bá wáyé pé a ó fọ̀rọ̀ wá ọ lẹ́nu wò
ojú-ewe 12

5 — Àwọn ohun ìrànwọ́
ojú-ewe 16





# 1

## Kọ́ nípa àwọn ẹ̀yàn ilé olowopooku rẹ



Ìgbáradì láti bèrè fún ilé tí kò wọ́n máa ń gba àkókò — ó sì ju kí o buwọ́lu ìwé nìkan lọ. Ìtọ́ni yìí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ṣètò dáradára kí o le tẹ pẹpẹ ìbèrè tó lágbára.

# Kínni ilé olowopooku?




A wòye ilé bíi olowopooku tí ó bá ṣeé rà ní iye owó ìdáméta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ nínú owó àpawọlé àwọn tí ń gbé ibẹ̀. Oríṣìí ilé olowopooku ló wà fún àwọn ẹbí pẹ̀lú oríṣìí owó àpawọlé.

Nínú ìtọ́ni yìí, "ilé olowopooku" túmọ̀ sí àwọn ibùgbé tó jẹ́ ara àwọn ètò ilé ti ko won ti ìjọba. Ó dojúkọ ilé tí New York City Department of Housing Preservation and Development (HPD) àti Housing Development Corporation (HDC) ṣe ẹ̀dínwò fún.

Àlàyé nínú ìtọ́ni yìí yóò ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ṣàmúgbòrò ìbèrè rẹ fún oríṣìí àwọn ètò ilé tí kò wọ́n—àti ilé tó wà nínú ọjà aládàáni, pẹ̀lú.



## Tani ó yẹ fún ilé olowopooku? Ẹnikẹ́ni ló le bèrè! Ṣùgbọ́n:

- O gbọ́dọ̀ jẹ́ ọmọ ọdún mejidinlogun ó kéré jù.
- Ó ṣeéṣe kí o nílò Nọ́mbà Ààbò Ìgbàlódé (SSN) tàbí Nọ́mbà Ìdánimọ̀ Ẹni Tí Ń San Owó-orí (ITIN).
- Àwọn olùgbé New York City máa ń ní ànfàní fún ilé HPD àti HDC.
- Owó àpawọlé rẹ gbọ́dọ̀ jẹ́ láàrín akata kan pàtó, èyítí àyípadà rẹ dá lórí iye àwọn ènìyàn tí ń gbé pẹ̀lú rẹ, a sì ń ṣètò rẹ̀ nípasẹ̀ ètò ilé gbígbé kọ̀ọ̀kan.



# 2

# Gbáradì láti bèrè



**O le ṣàmúgbòrò ìbèrè rẹ pẹ̀lú àwọn ìgbésẹ pàtàkì díẹ́. Ṣùgbọ́n àwọn ìgbésẹ́ wọ́nyí le gba ọ́pọ̀ oṣù láti parí—bẹ́rẹ̀ lónìí!**




## Mọ ìtàn gbèsè rẹ

Àwọn onílé kò le já ọ lórí ìgbéléwọ̀n gbèsè rẹ nìkan, ṣùgbọ́n wọ́n le yẹ ìtàn gbèsè rẹ wò. Ṣàrídájú pé àlàyé nínú ìjábọ̀ gbèsè rẹ tọ̀nà, kí o sì gbé ìgbésẹ̀ láti ṣàmúgbòrò ìgbéléwọ̀n gbèsè rẹ, tí o bá ní láti ṣe bẹ́ẹ̀.


- Gba ìjábọ̀ gbèsè rẹ lọ́fẹ̀ẹ́ ní annualcreditreport.com
- O lè yanjú àwọn àṣìṣe lórí ìjábọ̀ gbèsè rẹ nípa bíbèrè lórí ayélujára, nípasẹ̀ fóònù, tàbí fífi lẹ́tà kan ránṣẹ́ sí ilé-iṣẹ́ jíjábọ̀ gbèsè náà.
- Gba ìrànwọ́ láti lóye ìjábọ̀ gbèsè rẹ kí o sì kọ́ bí o ti le ṣàmúgbòrò ìgbéléwọ̀n gbèsè rẹ láti ọ̀dọ̀ olùdámọ̀ràn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ìṣúná owó, lọ́fẹ̀ẹ́. Lọ sí nyc.gov/consumers fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé, tàbí pe 311 kí o sì bèrè láti ṣètò ìpàdé kan ní ibi NYC Financial Empowerment Center kan.

## Mọ ìtàn Ilé-ẹjọ́ ilé rẹ

Àwọn onílé le ṣàyẹ̀wò bóyá a ti gbé ọ lọ sí Ilé-ẹjọ́ Ilé rí tàbí a ti fi ipá lé ọ jáde. Ṣàyẹ̀wò ìtàn rẹ ṣáájú àkókò kí o le yanjú èyíkéyìí ìṣòro, kí o sì ṣetán láti dáhùn àwọn ìbéèrè tó bá jẹyọ.

- Wá kí o sì tẹ àkọsílẹ̀ ìtàn rẹ lórí àwọn kọ̀npútà gbogbogbò tó wà nílẹ̀ ní àwọn ibi Ilé-ẹjọ́ Ilé. Lọ sí nycourts.gov/courts/nyc/housing fún àwọn ibi tó wà àti ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé.
- Palẹ̀ gbogbo ẹjọ́ tó wà fún ọ mọ́ nípa bíbèrè fún ìrànwọ́ láti ọ̀dọ̀ agbẹjọ́rò ní Ilé-ẹjọ́ Ilé, tàbí ṣàbẹ̀wò sí nycourts.gov fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí gbígba ìrànwọ́ òfin.






## Bẹ̀rẹ̀ sí ni fi owó pamọ́

O gbọ́dọ̀ fi ó kéré jù owó ilé oṣù méjì pamọ́ láti le yanjú oṣù àkọ́kọ́ àti àsansílẹ̀ ààbò. O le fẹ́ fi ọ̀pọ̀ owó pamọ́ láti le yanjú owó àkókiri rẹ.

- Bẹ̀rẹ̀ sí ni fi owó pamọ́ fún àkókiri rẹ nípa wíwá àkọọ́lẹ̀ ìpamọ́ kan tí ń fún ọ ní èlé pẹ̀lú ilé-ìfowópamọ́ tàbí alájọ èlé.
  - ✓ Tí o bá ní káàdì IDNYC kan, o le lòó láti ṣí àkọọ́lẹ̀ ìpamọ́ kan ní ọ̀pọ̀ àwọn ilé-ìfowópamọ́ àti alájọ èlé. Lọ sí: on.nyc.gov/idnycbanks láti mọ ibi.
  - ✓ Fún ìrànwọ́ láti ṣẹ̀dá èto-ìṣúná, ìpamọ́, tàbí ṣíṣí àkọọ́lẹ̀ ilé-ìfowópamọ́ kan, ṣàbẹ̀wò sí ibi NYC Financial Empowerment Center. Fún àlàyé, lọ sí nyc.gov/consumers tàbí pe 311 kí o sì bèrè láti ṣètò ìpàdé kan ní ibi NYC Financial Empowerment Center.



# 3

# Bèrè



**Kété tí o bá ti bẹ́rẹ̀ iṣẹ́ lórí gbèsè, Ìtàn Ilé-ẹjọ Ilé, àti ìfowópamọ́ rẹ, bẹ́rẹ̀ sí ni bèrè fún ilé olowopooku!**



## Ṣètò àkópọ̀-àlàyé ìsopọ̀ Ilé rẹ



Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́ láti bèrè fún ilé olowopooku ni láti ṣẹ̀dá àkópọ̀-àlàyé Ìsopọ̀ Ilé ní: nyc.gov/housingconnect

- Wàá nílò àlàyé nípa ti àwọn owó àpawọlé ti gbogbo ènìyàn tí yóo gbé inú ibùgbé náà.




★ Owó àpawọlé pẹ̀lú owó tí o pa lẹ́nu iṣẹ́ rẹ ojojúmọ́, níní òwò tí àdáni, àti/tàbí iṣẹ́ onígbà díẹ̀. Ó tún pẹ̀lú owó míràn tí o gbà láti owó àjẹmọ́nú òṣìṣẹ́, ìjọba (bíi Ààbò Ìgbàlódé tàbí ìrànwọ́ gbogbogbò), àti àwọn ìsanwó kan pàtó láti iṣòwò àti ìfẹ̀yìntì.

Ọ̀pọ̀ àwọn àlayé yìí yóò wà lórí ìdápadà owó orí tí o kọ ní ọdún tó kọjá.

Tí o bá ṣiṣẹ́ fún ẹlòmíràn, ṣafikún owó tí a san fún ọ ṣáájú owó-orí (tí a ń pè ní "àpapọ̀ owó àpawọlé"). Tí o bá ń ṣiṣẹ́ fún ara rẹ, ṣàfikún iye owó tí o pa lẹ́yìn owó orí àti àwọn àyọkúrò míràn (tí a ń pè ní "owó àmúrelé").

Tí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ síi láti lóye ohun tí a ń kà bíi àpawọlé, ṣàyẹ̀wò ìtọ́ni àpawọlé HPD fún àwọn olùbèrè ilé àìwọ̀n: nyc.gov/hpd/incomeguide

# Ṣàwárí àwọn ibùgbé


- Lo “Ṣàwárí” ojú-ìwé lórí Ìsopọ̀ Ilé láti wá àwọn àkójọ ilé àìwọ̀n. Ṣíra tẹ orúkọ náà láti kọ́ tí o bá yẹ fún tẹ́tẹ́ oríire ilé.

  > ★ A ń pèé ni tẹ́tẹ́ oríire nítorí bí ó ti ń ṣiṣẹ́ nìyẹn: gbogbo ìbèrè lọ sí àkópọ̀ ńlá kan a sì ń mú wọn lẹ́yọ kọ̀ọ̀kan.

- O le rí àwọn àkójọ náà nínú ìwé ìròyìn àti lórí ojúlé-wẹ́ẹ̀bù ti HPD àti HDC: nyc.gov/hpd àti nychdc.com

- Gbogbo àkójọ yóò ṣàfihàn iye àwọn ibùgbé tó wà nílẹ̀, iye ènìyàn tó le gbé inú ibùgbé kọ̀ọ̀kan, akata owó àpawọlé tí ẹbí rẹ gbọ́dọ̀ ní láti le yẹ, àti ìgbà tí ìbèrè náà yóò parí.






- Tí owó àpawọlé ẹbí rẹ bá pọ̀ jù tàbí kéré jù fún ilé náà, o kò ní yẹ. Bèrè sí àwọn tẹ́tẹ́ oríire fún àwọn ilé tó yẹ fún iye àwọn ènìyàn tí ń gbé pẹ̀lú rẹ kí o sì ṣàkópọ̀ akata àpawọlé ti iye tẹ ẹnìkọ̀ọ̀kan ń pa.

- Àwọn ibugbé kan wà tí a tọ́jú fún àwọn ènìyàn tó wà ní irú ipò kan pàtó, pẹ̀lú tí o bá:

  - ✓ Ní ìṣòro láti rìn, gbọ́ tàbí ríran
  - ✓ Ń gbé ní Ẹkun Àdúgbò kanáà
  - ✓ Ńṣiṣẹ́ fún Ìlú

  Tí èyíkéyìí nínú ìwọ̀nyí bá kàn ọ́, ṣàrídájú pé o fi wọ́n síi nínú àkópọ̀ àlàyé rẹ àti nínú ìbèrè tẹ́tẹ́ oríire rẹ.

- Jẹ́ kí àkópọ̀ àlà Ìsopọ̀ Ilé rẹ máa kójú òṣùwọ̀n. Fún àpẹrẹ, tí o bá ní iṣẹ́ titun tàbí pàdánù iṣẹ́ kan, ṣàrídájú pé o múu dójú òṣùwọ̀n. Ṣàyẹ̀wò àkópọ̀ àlàyé rẹ nígbà kọ̀ọ̀kan tí o bá bèrè fún ilé titun.

# Bèrè!

Tí o bá rí ilé kan tí o yẹ fún, ṣíra tẹ “Bèrè” tó kangún sí àkójọ náà láti bẹ̀rẹ̀ ìbèrè rẹ.

- O tún le kún ìbèrè àfọwọ́kọ kí o sì fíránṣẹ́ nípasẹ̀ méèlì.

  - ✓ Àkójọ kọ̀ọ̀kan yóò ní àlàyé lórí bí o ti le gba ìbèrè àfọwọ́kọ́.
  - ✓ Àlàyé yóò wà lórí ìbèrè náà tí ń sọ fún ọ ibi tí o le fíránṣẹ́ sí.
  - ✓ Ó le gba ọ̀pọ̀ ọjọ́ láti gba ìbèrè àfọwọ́kọ nínú méèlì, fún ìdí èyí tí ọjọ́ ìmúdópin bá ń súnmọ́, rò nípa kí o bèrè lórí ayélujára. Àwọn ìbèrè àfọwọ́kọ àti orí ayélujára ni a ń yanjú ní ọ̀nà kannáà nínú tẹ́tẹ́ oríire náà.

- Bèrè kí ó tó dópin! Ìgbà ìbèrè le pẹ́ láti bíi ọ̀sẹ̀ díẹ̀ sí bíi oṣù díẹ̀, fún ìdí èyí fún ara rẹ ní ọ̀pọ̀ àkókò.

- Níwọ̀n bí o bá ti bèrè kí ó tó parí, kò níṣe ìgbà tí o fa ìbèrè rẹ kalẹ̀.

- Àwọn ọ̀pọ̀ ìbèrè ni a le fagilé, fún ìdí èyí máṣe fíránṣẹ́ ju ìbèrè kan lọ. Bẹ́ẹ̀ni kí o máṣe fi ìbèrè àfọwọ́kọ àti orí ayélujára ránṣẹ́ papọ̀.


# Lẹ́yìn tí o bèrè

Ó le gbà tó ọdún kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ láti gbọ́ nípa ìbèrè rẹ. (Àti pé nígbà míràn o le má gbọ́ rárá.)

- Nígbàtí o ń dúró, rọra ṣàyẹ̀wò ohun tí àdéhùn ìyálégbé rẹ sọ ní ìsinsìnyí nípa kíkó jáde kí àdéhùn ìyálégbé náà tó dópin. Tí a bá fún ọ ní ibùgbé kan, o le ní láti kó wọlé ní kíá.

- Nítorí pé o yẹ kò túmọ̀ sí wípé a ó yan ìbèrè rẹ nínú tẹ́tẹ́ oríire náà.

- Tí a kò bá yàn ọ́ tàbí o kò gbọ́ láti ọ̀dọ̀ wa, máa wá àwọn ibùgbé míràn kí o sì bèrè nígbàtí o bá ṣetán.



4

# Gbáradì tó bá ṣeéṣe wípé o ní ìfọ̀rọ̀ wá ni lẹ́nu wò



**Tí a bá yan ìbèrè rẹ, a ó fìwé pé ọ́ fún ìfọ́rọ́ wáni lẹ́nu wò ti àyẹ́wò pẹ́lú àwọn aṣojú láti ilé náà. Ìfọ́rọ́ wáni lẹ́nu wò yìí ṣe pàtàkì púpọ́. Àwọn aṣojú láti ilé náà yóò ṣàrídájú tí o bá yẹ fún ibùgbé tí o bèrè fún. Gbáradì ṣáájú àkókò láti ṣàrídájú pé o múra sílẹ̀.**




## Kó àwọn àkọsílẹ̀ pàtàkì jọ pọ̀

Ní ibi ìfọ̀rọ̀ wáni lẹ́nu wò, wàá ní láti fi àwọn àkọsílẹ̀ kan hàn tó ṣàrídájú àlàyé tí o kọ sínú ìbèrè rẹ. Bẹ̀rẹ̀ sí ní gba àwọn ẹ̀dà lónìí!

Wàá ní láti ṣàfihàn:

- ◯ Ẹnití yóò gbé pẹ̀lú rẹ.
  Àpẹrẹ:
  – àwọn ìwé-ẹ̀rí ọjọ́-ìbí
  – Àwọn káàdì Ààbò Ìgbàlódé
  – àwọn ID àwòrán
- ◯ Àwọn owó àpawọlé gbogbo àwọn tí yóò gbé pẹ̀lú rẹ.
  Àpẹrẹ:
  – ẹ̀rí ìsanwó
  – àwọn owó àsanpadà tí owó-orí ìjọba àpapọ̀ tàbí ìpínlẹ̀
  – ẹ̀rí Ààbò Ìgbàlóde, ọ̀jọ̀gbọ́n, tàbí àpawọlé ànfàní ìrànwọ́ gbogbogbò
- ◯ Àlàyé nípa ibi tí o ń gbé lọ́wọ́lọ́wọ́.
  Àpẹrẹ:
  – àdéhùn ìyálégbé ìsinsìnyí
  – àwọn ẹ̀rí ìsanwó ilé
  – ìwé owó iná tàbí gáàsì àìpé
- ◯ Tí o bá nílò ìrànwọ́ láti gba àwọn ẹ̀dà ti àwọn àkọsílẹ̀ wọ̀nyí, lọ sí ojúlé-wẹ́ẹ̀bù HPD: nyc.gov/hpd/afteryouapply



## Gbáradì fún ìfọ̀rọ̀ wáni lẹ́nu wò àyẹ̀wò

Wàá gba lẹ́tà kan tàbí í-meèlì pẹ̀lú ìtọ́ni lórí bí o ti le ṣètò ìfọ̀rọ̀ wáni lẹ́nu wò àyẹ̀wò rẹ. Ẹnikẹ́ni tó jẹ́ ọdún mejidinlogun tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí yóò gbé inú ibùgbé náà ní láti lọ fún ìfọ̀rọ̀ wáni lẹ́nu wò náà.

- ◯ Láti ṣètò ìfọ̀rọ̀ wáni lẹ́nu wò rẹ, kàn sí aṣojú ilé náà tí a ṣàkójọ nínú lẹ́tà.
- ◯ Tún ṣètò ìfọ̀rọ̀ wáni lẹ́nu wò rẹ tí o bá ní láti ṣe bẹ́ẹ̀ nípa pípe nọ́mbà tó wà lórí lẹ́tà ní kíá—àwọn aṣojú míràn máa ń bèrè fún àkíyèsí wákàtí mejilelogun ó kéré jù.
- ◯ Àwọn aṣojú yóò sọ fún ọ irú fọ́ọ̀mù tí o ní lati mú wá. Tí o bá ní àwọn ìbéèrè, pe nọ́mbà tó wà nínú lẹ́tà.



## Lẹ́yìn ìfọ̀rọ̀ wáni lẹ́nu wò àyẹ̀wò…

O le ní láti ṣe àwọn ìgbésẹ̀ àbẹ̀wò kan láti ṣàrídájú pé ìbèrè rẹ ti parí. Lẹ́yìn ìyẹn…

◯ A le gba ìbèrè rẹ. Wàá ní láti gbé àwọn ìgbésẹ̀ díẹ̀ síi kí o tó pinnu tí o bá fẹ́ buwọ́lu àdéhùn ìyálégbé.

◯ A le fi ọ́ sí àkójọ ìdúró, èyítí o le pẹ́ tó ọdún méjì. Aṣojú le kàn sí ọ láti mú àlàyé rẹ dójú òṣùwọ̀n. Kàn sí wọn tí o bá fẹ́ kí a yọọ́ kúrò nínú àkójọ náà.

◯ A le fún ọ ní lẹ́tà ìkọ̀sílẹ̀ pé o kọ̀ yẹ àti ìdí fún èyí. Tí èyí bá ṣẹlẹ̀, o ní ẹ̀tọ́ láti pe ẹjọ́. Èyí túmọ̀ sí wípé wàá ní ẹ̀tọ́ láti ṣàlàyé ìdí tí o fi rò wípé ìpinnu náà kò tọ̀nà.

✓ Tí o bá fẹ́ pe ẹjọ́, ṣe ní kíá—o ní ọjọ́ iṣẹ́ 10 láti ọjọ́ ìfiránṣẹ́ ti lẹ́tà láti fa ìpẹ̀jọ́ kalẹ̀!

✓ Fa lẹ́tà kan kalẹ̀ sí aṣojú ilé náà láti ṣàlàyé ìdí tí o fi rò pé kò yẹ kí a kọ ìbèrè rẹ silẹ̀. Ṣàfikún èyíkéyìí àkọsílẹ̀ tó ṣàtilẹ́yìn fún ìpẹ̀jọ́ rẹ. Lẹ́tà ìkọ̀sílẹ̀ yóò sọ fún ọ ibi tí wàá fiṣọwọ́ sí.

✓ Àwọn aṣojú ilé náà yóò sàtúnwò ìpẹ̀jọ́ rẹ wọn yóò sì fi lẹ́tà kan pẹ̀lú àbájáde ránṣẹ́ sí ọ.




✓ Tí ìpẹ̀jọ́ náà bá yọrísí rere, yálà kí o gba lẹ́tà ìfọwọ́sí tàbí kí a fi ọ sórí àkójọ ìdúró.

✓ Tí ìpẹ̀jọ́ rẹ kò bá yọrísí rere, wàá gba lẹ́ta ìkọ̀sílẹ̀ kan. Tí o bá sì rò wípé àṣìṣe kan jẹyọ, o le kàn sí aṣojú náà (HPD tàbí HDC) láàrín ọjọ́ òwò márùún pẹ̀lú àròyé rẹ. Ṣàrídájú pé o ṣàfikún àlàyé tí o fi rò wípé àṣìṣe kan jẹyọ. Lẹ́tà yìí yóò sọ fún ọ irú aṣojú tí o le kàn sí àti bí o ti le kàn sí wọn.

◯ Tí a bá fi ọ sórí àkójọ ìdúró tàbí gba lẹ́tà ìkọ̀sílẹ̀, àwọn ìbèrè tí o ti fàkalẹ̀ sí àwọn ilé míràn sì wúlò. Máa ṣiṣẹ́ lórí gbígbáradì tó bá ṣẹlẹ̀ pé a yàn ọ́ fún ilé míràn!





# Àwọn Àkíyèsí

# Àwọn ohun ìrànwọ

W

A

D

I

E

S

I

I

WÁ KÍ O SÌ BÈRÈ FÚN ILÉ OLOWOPOOKU

nyc.gov/housingconnect

WÁ ÀWỌN ÀǸFÁNÍ ILÉ Ẹ`DÍNWÓ
ÌLÚ MÍRÀN

Ojúlé-wẹ́ẹ̀bù HPD:
nyc.gov/hpd/rentalopportunities

Ojúlé-wẹ́ẹ̀bù HDC:
nychdc.com/pages/Now-Renting.html

WÁ KÍ O SÌ BÈRÈ FÚN ILÉ OLOWOPOOKU

nyc.gov/hpd/findhousing

O TÚN LE GBA ÌRÀNWỌ́ LÁTI
AṢOJÚ ILÉ

Ìwọ̀nyí ni àwọn ilé-iṣẹ́ agbègbè.
Wá ìkan ní: nyc.gov/hpd/findhousingresources

GBÁRADÌ LÁTI BÈRÈ FÚN ILÉ OLOWOPOOKU
PẸ̀LÚ ÌMỌ̀RÀN ÌṢÚNÁ-OWÓ, AKỌ́ ṢẸ́ MỌṢẸ́
ÌFOJÚKOJÚ Ọ̀ FẸ́ NÍ NYC FINANCIAL
EMPOWERMENT CENTER

Ṣàbẹ̀wò sí nyc.gov/consumers fun ọ̀pọ̀ àlayé,
tàbí pe 311 kí o sì bèrè láti ṣètò ìpàdé ní
ibi NYC Financial Empowerment Center.

Iṣẹ́ àkànṣe yìí ni a parí ní àjọṣe pẹ̀lú Gbọ̀ngán fún Urban Pedagogy (CUP), ilé-iṣẹ́ tí kò sí fún èrè tí ń lo agbára ìyàwòrán ati iṣẹ́-ọnà láti ṣàfikún ìkópa òṣìṣẹ́ tó ní ìtumọ̀: welcometoCUP.org
Ti a ṣe nípasẹ̀ Maison Papercut: maisonpapercut.com · Àwọn àlàyé nípasẹ̀ Rebecca Clarke.

NYC | Housing Preservation & Development | Consumer Affairs | NYC HDC New York City Housing Development Corporation | CUP | MP | Citi Foundation citi | Mayor's Fund to Advance New York City